Bibeli fun awon omode



# Omobinrin to gbe leemeji

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.

Jairu Okunrin kan to je Okan ninu awon Olori Sinagoogu eniti On sin Olorun to si n ko awon eniyan ni oro Olorun.  Ni ojo kan, isele buburu kan sele si Jairu.  Omobinrin re to feran, to je Omo odun mejila saisan o nku lo.  Jairu mo pe Omobinrin n ku lo.



Enikan soso lole ran Omobinrin Jairu lowo.  Jairu jade lati wa Jesu ati lati mu wa si ile re.  Jairu mo pe awon ore re Olori esin won ko fowosi ti Jesu.



Jairu ko bikita rara.  O nilo lati wa iranlowo kiakia ki Omo naa ma baa ku.

Jairu ri Jesu laarin opo eniyan ti o yii ka.



O kunle leba ese Jesu. O wi pe Omobinrin mi kekere nku lo, iranse kunrin naa bebe "wa gbe owo re le Omobinrin naa ki ara re kole ya, ati pe yoo ye."



Jesu lo si ile Jairu
Sugbon Jesu ko le tete
debe nitori Opo eniyan.
Nitori Omobinrin kan ti n
se aisan fun odun mejila.
Oun si ti lo si odo opo
awon olutoju (to na ohun
gbogbo ti o ni) lai ri
iranlowo Kankan.  O gaso,
Oun si fe ri Jesu!



Kini ohun ti Obinrin naa se?  'O' so pe bi oun ba le fi owo kan aso Jesu, ara oun a si wale (ya) "Omobinrin naa mu ona pon" oun si lo taara si odo Jesu.  Nigba naa, oun na owo re o si fi kan aso Jesu.



IYANU! IYANU! Omobinrin naa si san, lesekese! Patapata! Oun naa si mo pe ara oun ti ya, oun ti ni okun ati gbogbo ara oun. Sugbon leyin naa ohun kan jade. 'Tani o fowo kan mi? Jesu beere, opo eniyan si n fowo kan-an. Sugbon Omobinrin ti a mu larada mo pe o fe ki oun soro nipa Iwosan naa. Ko si tiju, oun si so gbogbo itan igbesi aye re.

Leyin igba naa, Iranse kunrin kan jade wa lati ile Jairu, Oju re si koro lai ti soro jade. Oun si so fun Jairu pe Omobinrin re ti ku. O ti ku! Boya O le tipe, ti Omobinrin naa ba le duro, Boya, ti... iku Omobinrin Jairu to se iyebiye ti lo.



Nigba ti Jesu si gbo, oun si dahun, “Mase beru, gbagbo, ara Omobinrin re yoo si ya,” Bawo ni ko se soro fun Jairu lati gba Jesu gbo: pe Omobinrin re ti ku.



Ninu ile, Opo eniyan n sunkun won si n sofo omobinrin naa. Omobinrin naa ko ku, sugbon oun sun ni' Jesu so fun won bee, won si rerin-in sii. Oun mo pe Omobinrin naa ti ku ni.



Jesu si le gbogbo won sita, Oun si gbe Omobinrin naa ni owo re, oun wi pe 'Omobinrin kekere, dide.



Jairu wa nibe, Iyawo re naa wa nibe pelu. Ati awon Omo eyin Jesu meta naa wa nibe. Gbogbo won si gbo ohun Jesu. Se Omobinrin kekere naa to ti ku naa gbo o?

Omobinrin to ti ku naa gbo
ohun Jesu' to pase!
Emi Omodebinrin
naa si pada, oun
si dide lesekese,
Jesu si ji dide
ninu Oku re.



Enu si ya awon Obi Omodebinrin naa. Jesu so fun won pe ki won fun Omodebinrin naa ni ounje. Won ro bi inu won se dun to, bawo ni won se n dupe lowo Jesu. Fun ife iyanu ati agbara to lo lati da emi Omobinrin won pada kuro ninu Oku.



Omobinrin to gbe leemeji

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Maaku ori karun un,
Luuku ori kejo

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.